# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV N0 824 LAGOS SATURDAY JUNE 16, — JUNE 22, 1962. KOBO MEJI(2D)


### OYUN ODUN META ABO NI

# Obinrin Alarede Kan Fi Bi Lagido L'owerri

## Ọju A Ri To...

OWERRI—Gbogbo awọn ara abule Egbelu Ohube lẹba Owerri ni nwọn bẹrẹsi nsare sihin, sọhun lati lọ wo iran ni ile awọn ẹlabıyamọ ti C.M.S. nigbati nwọn gbọ wipe obinrin Ibo alarede kan, Nwngo Ekeocha, ẹniti o ti loyun lati nkan bi ọdun mẹta abọ sẹhin bi ọmọ, ati pe ọmọ ti o bi na lagido ni.

Onirohin wa sọ fun wa pe ọmọ-lagido na ni oju meji l'agbari bi t i ẹiyẹ owiwi, ori rẹ ri ṣorọ, ẹnu ati ọwọ rẹ jọ t'enia, sugbọn o ni iru ni'di bi ti ọbọ.

Obinrin agb'ẹbi, Iyafin Juliana Nwamadi, ẹniti o gba ẹbi ọmọ na, ni ọrọ na ṣe on ni 'kayefi,' nitori ọjọ ti on ti nṣe iṣẹ-agbẹbi on ko ri iru ọmọ bayi ri; gbogbo awọn ẹsẹ ọmọ na ni nwọn dabi t'ọbọ.

# Ijoba Fe Bere Ise Isana Ni Ilorin Laipe Yi

ILỌRIN—Eto ile-ṣẹ iṣana ṣiṣe ti awọn Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti ṣe ileri wipe awọn fẹ kọ si agbegbe ilu Ilọrin ti pari, nwọn si ti fẹrẹ kọ ile-iṣẹ na tan nisisiyi. Onirohin wa flye wa wipe a-gba-yanu ni ile-iṣẹ na ti nwọn nkọ si ẹhin-odi ilu, lọna teṣọn lati lọ si Omu.

Eleyi ni yio di ile-iṣẹ meji pataki ti awọn Ijọba yio fi da awọn ara ilu Ilọrin lọla, nitoripe laipẹ yi ni Minisita Alamojuto iṣẹ owo ati iṣẹ ọwọ, Alhaji Zana Bukar Dipcharima, ṣe ikede ni ile Igbimọ Apapọ l'Eko pe Ijọba Apapọ na ti t ọ j u owo tabua kan (£4 million) lati fi da iṣẹ ṣuga silẹ ni ibikan ti nwọn n p e ni Bacita lẹba Jẹbba ni agbegbe Ilọrin.

Minisiter na tun ṣe alaye wipe gbogbo awọn Ijọba Ipinlẹ yoku, bi Ijọba Ipinlẹ Iwo-Orun ni Ibadan, Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ni Ẹnugu ati Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Kaduna, ni nwọn da owo sinu iṣẹ ṣuga na.

O ni bi iṣẹ suga na ba bẹrẹ, awọn yio ma ri to ẹgbaa medogun (30,000) tanwun lọdọdun, eyi a si mu ki a ja'awọ kuro ninu a nra suga lati ilu okere; gbogbo enia a si ri iṣẹ ṣe.

# Munisifa Pe Awon Oni Bosi L'ejo

## Nwon Ni Ki Nwon Ye Ko Ero L'eko

EKO—Ẹjọ kan pataki ti nwọn f'ẹnu kan ni owurọ ana ninu Kotu-nla l'Eko ni eyiti awọn Munisifa ilẹ yi (Lagos Town Council) pe awọn ọmọ ibilẹ ti nwọn nfi bọsi (Native Bus Owners) ṣe iṣẹ kakiri Eko ati Yaba, awọn bi Elias Transport Service, Jimọ, Owolabi Benson Transport Service, Anice ati Union Nigeriau Transporters Services si Kotu wipe ki nwọn ko gbogbo mọto-bọsi wọn kuro lọna fun awọn.

(Wo yo ku loju ewe keji)

**E f'oju s'ona fun irohin Alhaji Tuntun kan lose ti mbo.**

# Awo Irawo

**Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.**

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Bi o ti ro wipe nkan a lo nibi ise re, o le mase be, sugbon ki o mo wipe nkan a lo daradara lona mi-ran, awon ore yio si ran o lowo.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Oro elo-bi yio gba akoko re, awon enia yio be o fun iranlowo; ti o ba fi ogbon se gbogbo re a lo dede.

ARIES (Mar 21-April20) Ose yi dara fun iwo oe... ere, sugbon ki o sora ti o ba nri nkan ti o mu pupo se ise.

TAURUS (April 21-May 20) Se adagaya laro ati lale ki o le fun ara re ni okun. Ko si ewu.

GEMINI (May 21-June 21) Jowo mase sa enikan lowo ki o ba ma ... ... enunum, sora lodo obirrin.

CANCER (June 22-July 23) Ojo isin-eke kan nbo e lokan; ma bi ... re lo ko si nkankan.

LEO (July 24-Aug 22) Ojo Jimo dara fun ... ti o bi le se ese yi awon ere kan ki o mole fun ... lo si ... ki o ko fun won nitori re ko si nkan rere nibe.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Enyin abiyamo, awon omo yin a tore ebun kan lowo yin, ki e fun won; awon/alejo kan a se rere fun enyin na.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Wa lo si ibi iranwiwo kan ti yio ya o le-na, mase pe nibe. Awon ti e jo nse ise-po moro re ni rere; wa ri nkan rere kan.

SCORPIO (Oct24-Nov 22) O da bi enipe wa lo be awon enia re wo ni ile yin, awon a si gba e to-wo tese, sugbon ki o sora, ki o mase yo ayo pupo ju.

SAGITTARIUS Nov 23-Dec22 Mase binu rara bi o ba ri nkan ibinu, ojo ose (Sunday) ni ojo rere fun o ni ose yi.

CAPRICORN (Dec 23-Jan 21) Ye se iyemeji, teramo ero nkan ti o ti nro lokan, mase jeki enikan sije lona.

---

# Minisifa Pe Awon Oni Bosi L'ejo!

## Nwon Ni Ki Nwon Ye Ko Ero L'Eko

(O bere loju ewe kini)

Iyen ni pe ki awon mase fi moto-bosi won ko ero kakiri ni ilu Eko ati Yaba nibiti moto-bosi awon Minisifa gbe nko ero gba lojojumo.

Nigbati akowe Kotu na pe ejo na, awon loya olukuluku dide, nwon si daruko awon ti o gba awon fun ejo na lati Adajo Kotu ti yio gbo ejo yi.

Lehin eyi ni Adajo Kotu na ni on pa a lase fun awon mejej (awon ti o p'ejo ati awon ti a pe lejo) wipe on fun won ni osu kokan ki olukuluku mu iwe-ejo ti nwon fe ro wa si Kotu, ki nwon to beresi ro ejo na ni perewu.

---

**Ema Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Losose**

# omi l'ayo na



**Awon** egbe agba-bolu af'esegba, **ti Asole** ti Cardiff (Goulie) Vearnco-**mbe** lu gbadi ihamo lati gba **bolu kuro** pelu asiwaju ti Arsenal, Strong (No. 9.) ati omo egbe ti Cardiff **paapa Mel** Charles (No. 6.) ti nwon gba **lodo Arsenal** laipe yi.

**Akatakiti** yi sele nibi ere bolu **ti nwon** gba n'ile Arsenal ti o **jasi okokan**–(1-1) omin.

# Eko Akete Ile Ogbon (3)

**Lati owo Olalekan Onatade**

GEGEBI gbogbo wa ti mọ wipe awọn Yoruba lo ni ilu Eko, ati pe bi aṣa ilẹ wa, nwọn pin adugbo ilu na si nkan bi ọna mẹfa. Adugbo ikinni ni Isalẹ-Eko, awọn si ni Eko gaan, ibẹ ni nwọn njẹ Ọba si, ibẹ ni ọpọlọpọ ile awọn oloye (ti awọn ọmọ Eko npe ni IGA) gbe wa. Isalẹ-Eko yi bẹrẹ nibiti mo sọ (ninu iwe-itan mi ti ọsẹ keji) wipe ti o ba ti bọ silẹ lati ori kereni atijọ ibẹ ni wa jasi.

## Ọmọ Oni-yoyo

Isalẹ-Eko yi lo ni oju-Ọlọbun, nibiti awọn ara-Eko ti gbe nma ṣe etutu fun ara-ilu, Ọba ati fun awọn ijoye. Isalẹ-Eko lọ titi de Idumọta, Ẹnu-Ọwa, Idumayigbo ati gbogbo awọn adugbo kekeke ti o yọ si Idolewo ni Oko-Awo titi ti o fi de Isalẹ-Gangan.

Ni aiye atijọ awọn ọmọ Isalẹ-Eko lọkunrin lobinrin ni igberaga diẹ (iyen ti nkuro nisisiyi) nitoripe nwọn gbagbọ wipe awọn nikan ni awọn ni ilu Eko. Awọn ọmọbinrin wọn ki i fẹ lọkọ ni adugbo miran afi ni Iṣalẹ-Eko. Awọn ọmọkunrin wọn fẹran a nṣe iṣẹ-apẹja, awọn obinrin wọn ni si ma ta a; nitorina ni a ṣe npe wọn ni "Isalẹ-Eko ọmọ-A-din-Yọyọ jẹ".

### BI OJU KO BA TI ẸHIN-GBẸTI

Adugbo keji ni Olowogbowo; adugbo yi bẹrẹ ni Ereko, Oke-Arin, Ita Balogun, Itọlọ, Ọflin Alakoro mọ Ẹlẹgbata. Iru-wa, Ogiri-wa, ni awọn ti nwọn tẹ Adugbo Olowogbowo do, ninu wọn ni a ti ri Aganyin, Saro, Kurumọ, Egun ati Ẹgba, nikẹhin ni awọn ara 'AWẸ (lati Ọyọ) to de, ti awọn na si di ara Olowogbowo. Bi awọn ara Awẹ yi ti ṣe de Olowogbowo, ma mọ sọ fun yin ninu iwe itan mi ni gbamiran.

Lẹhin titi Ita Balogun, Ereko, Broad Street, Alakoro Marina, Apọngbọn, Breadfruit, Martins, awọn ti o tun gba iyi ni aiye igbani ni Egerton Road, Bishop Street (ni Bishop Street yi ni emi alara paapa ti kọ kẹkẹ ologere ti awọn npe ni cycle gun ni 1918) ati John Street awọn oju ọna-titi yoku ti jiga-jigo ni.

Titi oju-ọna John Street, ti mo darukọ gbẹhin yi jẹki nniran ọkọ a-gbe-Poo kan ti a npe ni OKOKO-MAYIKO ti o gba oju-ọna yi kọja lati ibiti ile idalẹsi gbe wa ni Oke-Arin loni, ti nwọn npe ni ọja Ereko tuntun, nitoripe ni Oke-Arin kọ ni ọja Ereko gbe wa ni aiye atijọ.

### OJU KO LE TI EKO

ỌKỌ OKOKO-MAIKO YI jẹ ọkọ ti awa ọmọde igba atijọ fẹran lati ma fi ṣe iran-wiwo ti o ba ti ṣi ti o nko ẹru rẹ lọ. Ti o ba ti kuro ni John Street, a ya si ọwọ ọtun ni Idunmọta, a si fọn fere rẹ kara-kara ki awọn ti o nna ọja Ereko le ya kuro lọna fun un, nitoripe ibiti awa mọ ni Ọja Ereko bẹrẹ ni ẹhin Ṣọja Idunmọta (ile-gbigbe ni o wa ibiti Ṣọja Idumọta wa yẹn nigbana) titi ti o fi de ita Agarawu, nibiti awọn obinrin gbe nta aṣọ-gele ni a npe ni Ọja Ereko.

Ọja yi a ma kun tobẹgẹ tio fi jẹ wipe oriṣiriṣi iran ni a ma nri wo nibẹ; a si ma nkọrin bayi ti a ba ri nkan ti o ṣe ajoji lọdọ awọn ara ilu-oke:

Mo r'enmọ l'Ereko,
Aja w'ẹwu, o r'aṣọ,
Ode fila, o tun nyan,
Mo r'emọ l'Ereko.

Bi ọkọ yi ba ti nfọn fere rẹ ti mbọ fafa-fifi ni ọlọmọ ati ma gbe ọmọ wọn kuro loju ọna. Aye ṣoo olukuluku nigbana pupọ ti o fi jẹ wipe awọn baba kan wa ti nwọn ni ki nwọn ma tọju ọjakakiri. Ẹnikẹni ti ko ba tete kuro loju ọna, awọn baba yi a na ni atori. Nitorina ni a ṣe npe awọn baba na ni ATORI-BABA nigbana.

Lọfẹ ni nwọn si nnu awọn ATORI na lọdọ awọn obinrin ẹlọja, kosi si obinrin kan ti wọn ko le na l'atori na, iyen ni mo ṣe sọ wipe aye ṣoo pupọ lọjọ na lọhun, nitoripe bi ẹnikan ba ṣe bẹ lojọ ti ode oni, Ijọba a ba Oluwa rẹ s'ẹjọ arufin, a si lọ gb'ẹwa ni kirikiri.

Ti ọkọ yi ba ti fo ja oju-titi Ẹhinogba a nari ṣọrọ gba ita Agarawu, Palm Church (eyiti ẹ yi orukọ rẹ pada nisiyisiyi, ṣugbọn mo mbọ wa sọ itan idi rẹ ti nwọn fi npe adugbo yi ni Palm Church), Ita Faji; ni ita Faji yi wa tun ba awọn ATORI-BABA nibẹ ti nwọn a ma ja wọn ni paṣan wipe ki nwọn ko ẹru wọn kuro loju ọna.

Bi ọkọ yi ba de ọja Ararọmi bakanna ni wa tun ba awọn baba alatori yi nibẹ. Ararọmi ni a npe ọja ti ẹ npe ni Sangrosi (Sandgrouse) loni, lati oju titi Tokunbọ mọ Cow Lane ni nwọn ti ko ọja na si ibiti o wa wa loni.

Oju-irin ọkọ Okoko-maiko yi, nigbati o de oke oju-titi Tokunbọ, o ya bara gba Cow Lane, o wa yọ si oju-titi Igboṣere lẹhin ile-igbẹ ti o wa lẹhin King's-College. Lati ibẹ ni o gba lọ titi ti o fi lọ gun ori Kereni Alarun ti ọna okun ti a npe ni Five Cowrie Bridge, ki o to wa pari si eti odo Ọsa nibiti nwọn gbe kọ hotẹli nla kan ti nwọn npe ni Federal Palace Hotel si nisisiyi. Ni ibiti o di nkan pataki loni yi, ni awọn a-gbe-poo gbe nda iṣẹ wọn si ni atijọ, ọmọluwabi kan kii fẹ de ibẹ ni aiye atijọ.

Awọn adugbo ti o tun ṣe pataki lẹhin awọn meji ti mo ti darukọ siwaju yi ni awọn bi Ita Faji, Ẹpẹtẹdo ninu adugbo Ẹpẹtẹdo yi ni Okepopo, Ebute Ẹiyẹkọl — Ebute Ẹlẹfun, Oju orori Osho titi de ẹkule Abari wa), Ite-oku-igboro (Campos), Popo Aguda ati Ẹhingbẹti.

Ile-isinku (Cemetery) ni a mọ Ikoyi si ni aiye igbani, ko si si ọmọ Eko kan ti o jẹ gbadura wipe ki on lọ kọ ile-gbigbe ti on sibẹ nigbati awa nṣe ọmọde l'Eko.


## OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.

POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—ỌFẸ

# ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 824. SATURDAY JUNE 16. - JUNE 22, 1962.


## Ori Jaja "F'epo"

AWỌN oni-waka Imale ni orin kan ti nwọn fẹran lati ma kọ ti nwọn ba nṣe waasi lode bayi:

Rikọṣi pa wọn pọ,

Nwọn d'ọrẹ;

Ko tọjọ, ko t'oṣu,

Ọrẹ baje.

Orin yi ni o ṣe gẹgẹ fun ọrọ awa "Eleti-Ọfẹ" ti a o fi ṣe olori ọrọ wa ti ọsẹ yi lori ẹsun ati ikilọ kan pataki ti Ọgbẹni Jaja Wachuuku, Minisita alamojuto ọrọ okere ti Ijọba Apapọṣe ṣe lọjọ Satide ọsẹ ti o kọja nipa Ijọba ilu Ghana ni Oke Okun ti o wipe Ijọba na nwa iṣubu wa gẹgẹ bi orilẹ ede.

Ọgbẹni Wachuku ninu ọrọ rẹ, ni Ijọba Nigeria ti nṣe akiyesi ototu Ghana, Ọgbẹni Kwame Nkrumah ati awọn ọmọlẹhin rẹ ti pẹ lori abosi ikọkọ ati ti gbangba ti nwọn nṣe si wa ni ilu Nigeria lati le bi-wa-ṣubu.

## LORI ORO GHANA

O ni gbara ti ilu na ti gba ominira ni nwọn ti berẹ iwa-abosi yi si wa. Minisita na ni nwọn ṣe titi ni Oke-okun ko to, nwọn tun ran awọn enia wọn wa si igi-inu wa lati jẹ wa lẹsẹ ẹhin.

Ni gasikin, oni kọ ni ẹkun awọn oselu wa lori ọrọ ilu Ghana, nitoripe nigbati awọn oselu kan ni ilẹ yi berẹsi tọka si aiṣedede Ọgbẹni Nkrumah lori ọrọ awọn ara ilu rẹ ati awọn ajoji ti o nle jade lai gbọ tẹnu wọn, awọn Ijọba Apapọṣe wa yi kanna ni nwọn nfi ọwọ pa a lori ti nwọn ni ki o ma ba iṣẹ ọwọ rẹ nṣo.

A niran owurọ ọjọ ti Ọgbẹni Nkrumah fẹ gunlẹ si Nigeria fun abẹwọ ọjọ diẹ, ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Ọgbomọsho Parapọ pẹlu olori wọn Oloye Akintọla lọ ba Alhaji Tafawa Balewa, olotu Ijọba Apapọṣe jiroro wipe awọn fẹ ki o kilọ fun n nipa ilie ti o nle awọn ọmọ ilẹ Nigeria wa sil; laiṣẹ lairo.

Ni ọjọ keji, ẹtẹ ati abuku ni awọn oniwe-irohin kan ti Yaba bu lu awọn ti o lọ jiroro na.

Awa Eleti-Ọfẹ ko sọ wipe nkan ti Ijọba ilu Ghana nṣe dara lori ọrọ wa, ṣugbọn ki i ṣe oni ni o yẹ ki ori wa "F'epo" lori iwa-abosi Ghana.

Abọ ọrọ ni a sọ fun ọmọluwabi, bi o ba de inu rẹ, a di odidi.

# Iwe Si Olotu

## Nwon Korira Wa

Olotu, boya iwe ti mo nkọ yi ni yio jẹ a-kọ-mọ mi ki Ijọba ilu Ghana yi to wa mi wa si ilẹ Nigeria, nitoripe gbogbo wa ni nwọn nsọ lọwọ ati lẹnu nipa ọrọ ti o ṣẹlẹ larin awọn ara ilu Ghana ati Ijọba Nigeria nisisiyi.

Ọnṣin ọmọ iya mi, loni kọ ni a ti nṣe kilọ-kilọ fun nyin nipa ọta ti o wa larin wa ati awọn ara ilu Ghana.

Lọjọkọjọ ti ẹ ba ti wa ṣere bọlu gbigbo tabi ẹsẹ-jija, ti ẹ si bori wọn, ọta ni nwọn mọ nyin si.

Ki a sọ otitọ, awọn ara ilu Ghana na korira wa lọmọde, lagba. Gbogbo iṣẹ-owo ti a nṣe paapa ni nwọn ti nyọ wa lẹnu nibẹ.

Emi ni,

Koforidua Baba Arata.

## Nipa Oro Owo Atijo

Mo gba fun Ọgbẹni Ọpalẹyẹ fun iwe ti o kọ si yin ninu iwe "Eleti-Ọfẹ" ti ọsẹ ti o kọja yi nipa ọrọ owo-atijọ ti ijọba wa ni Nigeria fẹ kọ silẹ ninu ipari oṣu ti a wa yi.

Ẹ jọwọ, ẹ tun ba wa tẹ ọrọ owo na mọ awọn oṣelu wa leti, wipe asiko ti nwọn sọ wipe ki a ma mu awọn owo na wa si ile-ifi-ifowo-pamọ-si (Bank) fun ipaarọ ti kuru pupọ ju, ki nwọn jọwọ ba wa sun ọjọ na siwaju.

Gbogbo awọn enia wa ti nwọn wa ni ilu Oke, ati awọn ti nwọn wa ni abule ke-ke-ke ko tilẹ ti mọ nkankan nipa ikilọ ọrọ owo yi.

Ẹ jọwọ, ẹ maṣe jẹki ọrọ wa ki o su nyin, Olotu, ọkọ ọba ko ni ja nyin lẹsẹ.

Emi ni,

Ọyọ E. Falana

## Kini Ghana Se ?

Boya iwe mi yi le tete de ọdọ nyin ki iwe yin "Eleti-Ọfẹ" to jade, ẹ jọwọ mo bẹrẹ f'oji, ki ẹ fun mi laye lati bere ọrọ kan ti o njẹ mi lọkan lọwọ awọn oṣelu wa ti nwọn ni nkan ti awọn ara ilu Ghana nṣe nisisiyi ko tẹ awọn lọrun.

Ẹ jọwọ, kinni awọn ara ilu Ghana ṣe? Kinni Olotu ilu wọn, Ọgbẹni Kwami Nkrumah ṣe? Nigbati o bẹrẹsi le awọn ọmọ Nigeria kuro nilu rẹ, laiṣẹ, lairo, ẹ si f'ọwọ f'ẹran, ẹ nwo wọn.

Otitọ ọrọ bi isọkusọ ni o nri; awọn ara ilu Ghana ti ri wa tan ki nwọn to ma sọ ọrọ-alebu ara wa.

Kinni awọn ara ilu Ghana ṣe fun wa ti awa alara paapa ko ti ṣe ilọpo meji rẹ fun ara wa?

Emi ni,

Kumasi A. Adejunmọ

# ELETI - OFE DARABA

# Nihin Lohin Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Egbe Olomo Tuntun

Inu mi dun pupọ lati ri ọrẹ mi atijọ, Oloye Akintọla ninu Ọla-nla rẹ ni Oke Taki ni Ogbomọshọ ni ọjọ Alamisi ti o kọja yi. Nigbati mo pade Baba Ogbomọshọ na (Oye tuntun ti emi Ayiluka fun Oloye Akintọla niyẹn), mo ri ami aisun aiwo ni oju rẹ; nigbati mo bere kilo 'fa lọwọ ẹnikan ninu awọn alatilẹhin rẹ, nwọn ni o to ọjọ karun ti o ti f'oju kan orun.

Mo ni bẹni ti ẹ ri! Emi alara paapa mọ wipe o ni lati ṣe wahala pupọ ki o to le gbe ẸGBẸ ỌLỌMỌ-TUNTUN yi de ibikan. Nitotọ aṣọ tuntun a ma ṣe ni tode-tode. Bi iyawo ba ṣẹṣẹ ni aṣọ-tuntun, ode a ma wu lati lọ.

Emi na fẹ wọ Ẹgbẹ Ọlọmọ-tuntun yi, ṣugbọn iru Oye wo ni nwọn yio fi mi jẹ nibẹ. Mo fẹ ki nwọn si ha emi paapa ni owo ijoko-agba ati owo awọn "BODA-O-WA," nitoripe mo ni awọn ọmọ "Boda-o-wa" pupọ lẹhin ati awọn ỌLẸ-NTẸLE-ALUFA. Ki iṣe awada, ẹnu mi dun pupọ, mo mọ kanpe (tabi bawo ni ẹ npe?) ti abẹ-ile ati ti gbangba ode ṣe pupọ.

Baba Ogbomọshọ, ẹ jọwọ, ẹ ma gbagbe mi bi ẹ ba de Ijọba yin.

### JAJA F'AKE KỌRI

Mo lọ si ile-iṣẹ ọrẹ mi Ọgbẹni Jaja Wachuku, Minisita Alamojuto ọrọ awọn nkan okere laipẹ yi; nigbati mo de ibẹ mo ri ti o fa oju ro kokoko. Mo ni kilo de? O ni ọrọ-abosi ti awọn Ijọba Ghana nṣe si Nigeria nisisiyi ni o mba on lọkan jẹ, o ni iyawo on din ẹyin-adiẹ aladun fun on nile, on ko le jẹ ẹ.

Jaja, ara Aba Ngwa, ọmọ afada yanju ọrọ, o se pupọ, sugbọn oni kọ ni awọn ara ilu Ghana ti nfojudi wa. Emi ti "na Pọta, mo si ti na Kalaba" ni ilu Ghana. Mọ lọ Kumasi, mo lọ Tarkoradi; mo ba wọn jẹ KẸNKI ninu igbo Tarkwa, mo si ba wọn jẹ BANKU ni ilu Accra; mo ba Dokita Nkrumah ṣe kanpe fun ẹgbẹ C.P.P. ni ita-gbangba kan ti nwọn pe ni Arẹna ni ilu Accra yi kanna.

Nitorina mo mọ iha ti awọn Aganyin kọ si wa lọtun losi. Ọrọ wa pẹlu ilu Ghana dabi ọrọ orogun meji. Ifẹ oju ni nwọn ni si wa. Sugbọn kinni awọn oṣelu wa nwo nigbati awọn ọmọ Aganyin ntu itọ-ẹnu si awọn elere-bọlu wa lara, nigbati nwọn nle awọn ọmọ Nigeria kuro nilu? Kaka ki nwọn ba wọn wi nṣe ni awọn ẹgbẹ oṣelu kan nkan sara si wọn.

Jaja, jọwọ lọ mu tii (tea) rẹ, ki o si jẹ ẹhin adiẹ, nitoripe Dokita Nkrumah mọ ayo ta daradara, o nkun ODU rẹ lọwọ ni, bi ẹ ko ba sọra daradara, a pa yin layo.

### OWO L'OBIN...

Ṣe ẹ niran irohin kan ti mo so fun yin laipẹ yi wipe awọn iyawo-asiko kọ ni pe mo pada wa sile lati Ibadan nitori awọn ọkọ asiko gbogbo ti Adekọyejo ọmọ Majekodunmi ti ge niyẹ nile Oluyọle. Awọn meta ninu awọn ọmọ wa eleyinju-ẹge ni ni mo ba pade ni ile-oti kan nibiti a nṣe igbadun ni ale ana. Ọkan ninu wọn ro ẹjọ fun mi titi, o ni nwọn gba moto ti nwọn fi dara ọkọ on lọla nidi rẹ, ati bi wọn ko ti fọwọ si iwe owo awọn nibiti awọn gbe ngba owo.

Morẹnikẹ (oruko eleyinju-ẹge na niyẹn) ni kosi fara-ji tobe mọ ni Ibadan nitorina ni awọn ṣe wa sile. Bi o ti nsọrọ yi lọwọ, ti a ti nmu oti-biya, ti a nmu siga, ti a nfi ikan ran ikan, bẹni onilu ti o wa niwaju ilu sii, ti o nkọrin bayi;

O gbọdọ ṣe tiwa; O gbọdọ ṣe tiwa  
Morẹnikẹ jojolo,  
O gbọdọ ṣe tiwa;  
Iyabọde jojolo,  
O gbọdọ ṣe ti wa;  
Aronkẹ jojolo,  
O gbọdọ ṣe tiwa.

"Ọrọ na wa di ọrọ, "a ko f'awa ti a gbe nsere, awa ko mọ wipe ebi npa ọmọ ẹnikan."

---

# Awon Oselu Mali

## Se Abewo ilu Bristol



Awon enia meji ninu awon alamojuto ilu Mali ni nwon wa ninu aworan yi nigbati nwon lo se abewo ebute-oko ni ilu Bristol. Eniti o wa ni apa otun won ni Ogbeni oyinbo kan ti nwon npe ni John Corrin, oga ile ise ebute ilu Bristol na ti o nmu awon alejo Ijoba Geesi na kakiri

## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

PORTS ACT (CAP. 155)

Nigerian Ports Authority (Election) Regulations, 1956

ELECTION OF ELECTED MEMBERS OF THE AUTHORITY, 1962.

NOTICE IS HEREBY GIVEN THAT in accordance with the Nigerian Ports Authority (Election) Regulations 1956, a provisional Ships Dues Register and a provisional Harbour Dues Register containing the names of those persons who are qualified to have their names entered on the respective Registers for the 1962 election of elected Members of the Authority, in accordance with the provisions of paragraph 5 of the Fifth Schedule to the Ports Act (Cap.155) (together with the address of each such person and the number of votes to which he is entitled) have been deposited, together with a copy of the said Regulations at –

the Head Office of the Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos –

and at the under-mentioned Principal Offices of the Authority in each of the following Ports :–

| | |
|---|---|
| Lagos | – Accounts Department, Apapa Quays Offices, Apapa. Dock Superintendent's Office, Apapa Quays, Apapa. Dock Superintendent's Office, Customs Quay, Lagos. Dockyard Manager's Office, Apapa Dockyad, Apapa. |
| Port Hartcourt | – Port Manager's Office, Customs Road, Port Harcourt. Accounts Office, Port Harcourt. Dockyard Manager's Office, Port Harcourt. |
| Burutu | – Custom House, Burutu. |
| Calabar | – Harbour Master's Office, Calabar. |
| Degema | – Custom House, Degema. |
| Sapele | – Transport Offiice, Sapele. |
| Warri | – Harbour Master's Office, Warri. |

2. Copies of the provisional Registers may be inspected at any of these offices during working hours up to and including the 28th day of June, 1962, without payment of any fee.

3. Persons requiring copies of the said Registers will be required to pay the sum of 1/- for each Register.

4. Any person qualified to be on either the Ships Dues Register or the Harbour Dues Register may, by notice in writing, stating the nature of his objection delivered to the Secretary to the Authority not later than the 28th day of June, 1962, object to the provisional Register concerned on the ground that his name, qualification or votes are omitted therefrom or incorrectly stated therein, or that the name of an unqualified person is included therein, or that the name, qualification or votes of a qualified person are incorrectly stated therein.

5. When any person makes objection to any name, qualification or votes entered on one of the Registers, other than his own name, qualification or votes, he shall at the same time as he delivers notice of such objection to the Authority, deliver to the person to whom the entry objected to relates, a copy of the notice of objection which he has delivered to the Authority, and without the delivery of such copy of the notice, no such objection shall be valid.

Dated this 26th day of May, 1962.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

N.P.A. NOTICE No. 711.

# Idaraya Fun Ere–Ije



Aworan ti ẹ nwo yi niti Ọmọbinrin kan ti oruko rẹ njẹ Ann Charlesworth, ọmọ ẹgbẹ asare-ije fun ilu Gẹsi ti o tun jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Yorkshire Club, Airedale Harriers, nibiti nwọn gbe nkọ ọ bi a ti nlo agbara fun ere-ije ni ile-ẹkọ awọn asare-ije ti nwọn npe ni Central Council for Physical Recreation Centre ni ilu Oyinbo, Ọgbẹni H. B. Campbell, Oluko pataki ni o duro ti obinrin na, ti o nkọ bi a ti se nlo orunkun ati ibaradi.

# Govt. Warns On Outside Savings

## 'Sell All Your Foreign Currency To Banks Here'

ACCRA—The Government has reminded Ghanaians that they should sell any foreign currency they possess to a bank in Ghana, a statement issued by the Ministry of Finance said here today.

The statement warned that Ghanaian holding funds outside the country were contravening the Exchange control Act, 1961.

It said: "In a recent comment in a local newspaper it was alleged that an ex-Minister was maintaining foreing banking accounts.

"From the comment, it may be inferred that there is at present no obligation for residents of Ghana to surrender any foreign funds they have in exchange for Ghana pounds until called upon to do so by the exchange Control authorities. This is not correct."

### Obligation

The relative obligation imposed on residents of Ghana by the Exchange Control Act. 1961, was that in the absence of any exemption, they must sell any foreing currency they possessed to a bank in Ghana."

It said that for the time being, Ghana residents who were not Ghanainian nationals were exempted administratively from this obligation but any Ghanaian national who was holding funds outside Ghana was contravening the act.

"Furthermore, amongst other obligations imposed under the act, every Ghanaian national must have any foreign securities he owns held by a bank in Ghana.

### Penalties

"Any such person owing foreign securities which are not held by a bank in Ghana is contravening the act.

"There is, therefore no question of being "called upon" to fulfil those obligations; they are specified within the Act itself and the penalties for not complying with them are severe" the statement added.

---

**Read And Advertise in the Eleti-Ofe News-Paper**

---

**Watch this Column next week for more news**

---

# BBC Discuss Psychology, Superstition And Luck

LONDON-Foretelling the future by the movement of birds is an ancient practice that the Romans believed in so implicitly that special priests, called "augurs," were appointed for this purpose and no action was ever taken without their advice. Superstitions like this are still in force today all over the world; in some parts of East Africa, for instance, great importance is still attached to the flight of birds, while in West Africa some people think that it is unlucky to rest a hand on the ground when eating.

In Europe there are many superstitions - 13 is an unlucky number, a black cat is lucky and it is thought to be asking for trouble to walk under a ladder.

Students of superstition find that psychology plays a great part in it and this forms the main talking-point of the BBC programme AFRICAN FORUM on Wednesday, June 20.

"Psychology, Superstition and Luck" is the the title of Wednesdays AFRICAN FORUM, which will be broadcast from the city of Leeds in the North of England at 11.00 GMT on 16.84 and 13.88 metres.

The guest speaker will be John Cohen, Ph. D., Professor of Psychology at the University of Manchester. During a very full career Professor Cohen has been a member of the Inter-professional Advisory Committee to the world Federation for Mental Health and a Consultant to UNESCO. He takes particular interest in African superstitions and says that he is looking forward to being questioned on such matters by the African students who are in Leeds. The Chair will be taken by the Ghanian barrister, W. C. Ekow Daniels.

---

## High Prices For Benin Bronzes In London Sale

LONDON — High prices were realised for West African art treasures sold in London this week.

A London dealer paid £4,350 for two Benin bronze heads at Monday's sale at Sotheby's, the Bond Street Auctioneers.

Bata
QUO VADIS



ni iru asa temi !

Awọn Sanda i ti a ṣe fun awọn ti o nwa iru aṣa......aw n sandali ti a ṣe lati funni ni itura pẹ titi ..sandali ti "BATA" kan wa, eyiti a ṣe fun olukuluku onibara. QUO VADIS ni i r u aṣa tirẹ. O daju-to ọla gẹgẹbi owo rẹ ti ṣe rọju julọ loni.



Style 44 27/6



Style 43 32/6



Style 42 27/6

Bata AKAN BATA FUN GBOGBO AGBAIYE
P. O. Box 548 Lagos, Nigeria.
EKA ILE-IṢE RE WA KAKIRI NAIJIRIA

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23 70; OLOTU: OLA. ONATADE, 15, Kosoko St., Lagos.

## Majekodunmi Pe Ipade Awon Oba Ati Ijoye

IBADAN—Ni oke Agod ni owurọ ana, ni ile iṣẹ-Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, gbogbo awọn akọwe-agba ati awọn iranṣẹ wọn ni nwọn nsare sihin sọhun lati tẹ waya si gbogbo awọn Ọba ati Oloye ti nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ Ile Igbimọ awọn Oloye Ipinlẹ Iwọ Orun na ti Dokita Adekoyejọ Majẹkodunmi, Alamajuto-tuntun ti Ipinlẹ na paṣẹ wipe ki nwọn wa si ipade pataki kan ti on fẹ ba wọn ṣe ni ile igbimọ wọn na ni ọjọ mọkanla (Tuesday, June 26) loni.

Onirohin wa ni Ibadan ni ko si ẹnikan ti o mọ nkan ti Alamojuto yi fẹ ba wọn sọ, ṣugbọn nwọn ṣe ẹnuforo fun wa wipe o fẹ ba wọn jiroro bi ilu yio ti ṣe toro jake-jado Ipinlẹ na ni. Lẹhin eyi, Dokita Majẹkodunmi a pe wọn si ibi ase-ikini-ku-abọ kan ninu ọgba Ile Ijọba ti o ngbe, ni irọlẹ ọjọ na nibiti yio gbe fi nkan mumu ati jijẹ tọ wọn lẹnu wo.

A tun gbọ wipe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun na fun si ti nmura lati san owo irinẹsẹ ọjọ na fun fun gbogbo wọn ti nwọn ba wa si ibi ipade na.

## Owo Atijo Tun Di Nina

NI oru alẹ ana ni awọn Ijọba tun fi ikede kan sode nipa owo atijọ ti nwọn ni awọn fẹ parẹ lati ipari oṣu yi lọ, nwọn ni awọn tun sun ọjọ piparẹ awọn owo na siwaju diẹ si.

Nwọn ni ti o ba di oṣu mẹta loni (September) ẹnikẹni ko ni gba gẹgẹbi owo-nina mọ ni ṣọbu, ṣugbọn lẹhnna, awọn ile if'owo-pamọ (Bank) ni yio mo gba wọn fun iparọ, nwọn o si tun ma a gba owo-iparọ (commisson) lori wọn titi di inu oṣu (December) ipari ọdun yi.